**AIGBAGBỌ́ ENIYAN NIPA BIBỌ̀ KRISTI**

**2 Peteru 3: 1-18.**

**ẸKỌ 456 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ibukún ni fun ọkunrin na ti kò rin ni imọ awọn enia buburu, ti kò duro li ọ̀na awọn ẹlẹṣẹ, ati ti kò si joko ni ibujoko awọn ẹlẹgàn" (Orin Dafidi 1:1).**

**I. Awọn Ẹlẹgan Sẹ́ Bibọ̀ Oluwa**

1. Eredi iwe Peteru ni lati ru ifẹ awọn Onigbagbọ soke nipa riran wọn leti, 2 Peteru 3:1, 2; 1:12.
2. Awọn ẹlẹgan ti wọn n rin nipa ifẹkufẹ ara wọn, n wi pe, "Nibo ni ileri wiwa rẹ̀ gbé wà?" 2 Peteru 3:3, 4; Orin Dafidi 73:11; 1 Kọrinti 1:21.
3. Wọn mọọmọ ṣe aifẹmọ pe nipa Ọrọ Ọlọrun ni a dá ayé igba nì ti o si tun ṣegbe ninu Ikun-omi nipa Ọrọ kan naa, 2 Peteru 3:5, 6; Heberu 11:3.

**II. A Pa Ayé Isisiyii Mọ́ de Idajọ**

1. Ayé ti o parun ninu Ikun-omi nipa Ọrọ Rẹ̀, yoo parun ninu iná nipa Ọrọ kan naa, 2 Peteru 3:7; 2:5.
2. Awọn ileri Rẹ̀ yoo duro, Ẹni ti ẹgbẹrun ọdun dabi ọjọ kan lọdọ Rẹ̀, 2 Peteru 3:8, 9; Orin Dafidi 90:4; Isaiah 40:8.
3. Ọjọ Oluwa n bọ̀ wa bi ole ni oru nigba ti a ba pa awọn ọrun ati ayé run, 2 Peteru 3:10, 1 Tẹssalonika 5:2, 3; Ifihan 6:14; 16:15.

**III. Imurasilẹ fun Ọjọ Oluwa jẹ́ Dandan**

1. Bi awọn Onigbagbọ́ ti mọ pe gbogbo nnkan wọnyii n bọ wa ṣẹ, wọn ni lati maa rin ninu iwa mimọ́, 2 Peteru 3:11, 12; Matteu 24:35.
2. Ifojusọna si ọrun titun ati ayé titun ni lati rú itara soke, 2 Peteru 3:13, 14; Isaiah 65:17; 66:22; Ifihan 21:1.
3. O ṣe ohun danindanin lati ni oye awọn nnkan ti Ọlọrun ati lati dagba ninu oore-ọfẹ, 2 Peteru 3: 15-18; 1:10, 11; 2 Timoteu 2:15.

## ALAYE

**Rirú Ọkàn Wọn Soke**

Ninu Episteli keji ti Peteru, o fi ọkàn funfun ti awọn Onigbagbọ́ ni wé ọkàn ibajẹ ti a ṣe apejuwe rẹ̀ ninu ori iwe ti o kẹyin. O n mu awọn asọtẹlẹ ti awọn wolii mimọ́ ti igba Majẹmu Laelae wá si iranti wọn, lati ṣe alaye lori wọn ati lati mu wọn lò. O si n fi aṣẹ awọn Apọsteli Oluwa ati Olugbala kún wọn pẹlu.

**Awọn Ẹlẹgan Nikẹyin Ọjọ**

Ikẹyin ọjọ ti Peteru sọ nipa rẹ̀ n tọka si opin akoko tabi igba ti a wà yii. Awọn ẹlẹgan ninu ifẹ ọkàn wọn eyi ti i ṣe ofin wọn, ni Ọrọ Ọlọrun ati awọn asọtẹlẹ ti o wà ninu rẹ̀ ko jamọ nnkankan fún. Gẹgẹ bi asọtẹlẹ Peteru, awọn eniyan wà lode oni ti a n fi eke pè ni awọn "ẹlẹkọ ijinlẹ". Ninu oye ati ọgbọn ayé wọn, ibeere kan naa ti Peteru wi pe wọn o maa beere ni o wà lẹnu wọn pe, "Nibo ni ileri wiwa rẹ̀ gbé wà?" Wọ́n fi ọgbọn-ori wọn sọ pe ilepa ayé ati ohun gbogbo ti n ṣẹlẹ ko dẹkun lati ọjọ iwà. Igba ẹẹrun ati igba ojo n wá o si n lọ; bakan naa ni a n bi ọmọ ti awọn eniyan si n kú; ọjọ si n kọja lọ bakan naa.

Awọn alaigbagbọ́ ati alailofin wọnyii n gbé ofin ẹda ga ju Ọlọrun ẹlẹda lọ ati ifihàn Rẹ̀. Ẹlẹṣẹ mọ pe Iwe Mimọ́ n kọ́ ni nipa ipadabọ Kristi; ṣugbọn ọ̀rọ ijiyan rẹ̀ ni pe bi ọjọ ti n yi lu ọjọ ati ohun

gbogbo ti o ti ṣẹlẹ ko jẹ ki idilọwọ kan wa ni ti akoko ti o bọ niwaju. Wọn gbagbọ pe lati atetekọṣe ni ohun gbogbo ti wà gẹgẹ bi o ti wà nisisiyii, ati pe ayé yii yoo si maa wà titi lae, boya fun aimọye ọdún. Ko si àye ninu ọrọ arofọ ọgbọn-ori yii fun ẹkọ ati awọn ileri ti o wà ninu Ọrọ Ọlọrun. Boya iru aigbagbọ́ yii ni ẹ̀ṣẹ ti awọn eniyan igba ayé Noa dá. Iru iwa bayii ni a sọ asọtẹlẹ nipa rẹ̀ ninu ori ẹkọ yii.

**Fifi Mimọ̀ Ṣe Aimọ̀**

Peteru n sọ fun wa pe wọn n fi mimọ̀ ṣe aimọ̀. Ko si ẹni ti oju rẹ̀ fọ to ẹni ti o kọ̀ lati riran. Awa ti a gbagbọ́ n kà lati inu Ọrọ Ọlọrun pe, "Nipa igbagbọ́ (ki i ṣe imọ ijinlẹ) li a mọ̀ pe a ti da aiye nipa ọ̀rọ Ọlọrun" (Heberu 11:3). "Ọlọrun si wi pe, Ki imọlẹ ki o wà: imọlẹ si wà". Nipa Ọrọ Rẹ̀ pẹlu ni ayé kan naa ti Ọlọrun dá parun ninu Ikun Omi. O ṣe e ṣe ki awọn eniyan igba ayé Noa maa rò pe nigba ti kò si ikun omi ri, ati pe ohun gbogbo wà gẹgẹ bi o ti wà ri, ikilọ Noa si wọn, gẹgẹ bi o ti n kan ọkọ jẹ́ ohun yẹyẹ. Bẹẹ gẹgẹ ni ayé isisiyii "li a ti tojọ bi iṣura fun iná, a pa wọn mọ́ dè ọjọ idajọ" (2 Peteru 3:7). Lootọ fifi iná pa ayé yii run ki yoo gbà ju ẹgbẹrun ọdun lọ nitori ni opin igba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun ni yoo ṣẹlẹ.

**Akoko Ọlọrun ati Akoko Eniyan**

Peteru sọ fun wa ninu ẹsẹ kẹjọ pe ẹgbẹrun ọdun lọdọ Ọlọrun bi ọjọ kan ni o ri ati ọjọ kan bi ẹgbẹrun ọdun. A n kilọ fun Onigbagbọ́ ki o má ṣe fi odiwọn eniyan wọn ohun ti Ọlọrun. Aṣiṣe ti awọn ẹlẹgan igba ikẹyin ọjọ n ṣe ni eyi. Oluwa ko fi ileri Rẹ̀ jafara bẹẹ ni ko fasẹyin ninu ilana Rẹ̀. Eniyan ni o n pẹ ju ti o si n jafara. Ohun ti o dabi ifasẹyin tabi ijafara loju eniyan ki i ṣe ohun miiran bi ko ṣe ipamọra ati aanu Ọlọrun. Oun ko fẹ ki ẹnikẹni ki o ṣegbe, ṣugbọn ki gbogbo eniyan ki o le wa si ironupiwada. O dá ayé ẹ̀ṣẹ yii sí ki o le fún un ni anfaani lati ronupiwada. Abajọ ti Onipsalmu fi wi pe, "Ãnu rẹ̀ duro lailai" (Orin Dafidi 106:1).

**Ọjọ Oluwa**

Ọjọ Oluwa yoo de ba awọn ẹlegan lai ro tẹlẹ. Wọn ki yoo le jiyan mọ pe nigba ti awọn baba ti sùn, ohun gbogbo n lọ bi wọn ti wa ri lati igba didá ayé. A sọ nipa Ọjọ Oluwa ninu Isaiah 2:10-22 ati Ifihan 19:11-21. Ọjọ yii ko tọka si wakati mẹrinlelogun ti o ó wà ninu ọjọ kan, ṣugbọn o tọka si akoko igba ti Oluwa yoo ṣe idajọ ayé ati awọn eniyan inu rẹ̀. Ni akoko ti Ọlọrun ti yàn, idajọ Ọlọrun yoo dé. Ni ipari gbogbo rẹ̀, awọn ọrun yoo kọja lọ pẹlu ariwo nla; awọn imọlẹ oju ọrun yoo si ti inu ooru gbigbona gidigidi di yiyọ́. Ayé yii ati gbogbo iṣẹ ti o wà ninu rẹ̀ yoo jona luuluu, Ayé ti ẹ̀ṣẹ ti sọ di eeri yii yoo kọja lọ (Wo Matteu 24:35 pẹlu).

**Ojuṣe Awọn Ẹni Ti O Ni Imọ**

Bi a ti ni imọ awọn ohun wọnni ti o n bọ wa ṣẹ, Apọsteli ni beere pe "Irú enia wo li ẹnyin iba jẹ" ninu iwa mimọ́ gbogbo ati imọ pe Ọlọrun wà n tosi, ki a si gbẹkẹ wa le E? Ki a maa reti nigba gbogbo, ki a si maa mura giri de didé Ọjọ Ọlọrun, ki i ṣe ninu ibẹru, bi ko ṣe ninu ireti Onigbagbọ́. Awa ko wi pe, "Bawo ni awọn nnkan wọnyii yoo ṣe ri bẹ́ẹ̀?" Niwọn bi iran ayé isisiyii ti ri ọta oloro oju ọrun ti n ṣe iparun, o yẹ ki o yé wọn bi yoo ṣe rọrun fun Ọlọrun lati mu ọrọ asọtẹlẹ yii ṣẹ. Awọn ohun ti o wà ninu ayé ti di yiyọ́ ninu ooru gbigbona nibikibi ti a ba yin iru ọta oloro yii si. Gbogbo awọn ẹni ti o wà ni agbegbe ibi ti ọta wọnyii ti balẹ ni o kún fun iwariri nitori ariwo ati iná ọta wọnyii, bẹẹ ni irọkẹkẹ ati ooru nla ti o tẹle ọta wọnyii ti sọ ohun gbogbo ti o wà ni ipa ọna wọn di okú.

**Ọrun Titun ati Aye Titun**

Gẹgẹ bi itunu ati iwuri fun gbogbo awọn ti n gbé igbesi-ayé ẹni iwa-bi-Ọlọrun a ni ileri ọrun titun ati ayé titun, nibi ti ododo n gbé. (Wo Isaiah 65:17; 66:22; Ifihan 21:1). Bawo ni yoo ṣe jẹ́ ohun ajeji tabi iṣoro fun Ọlọrun lati dá ọrun titun ati ayé titun nigba ti o jẹ pe Oun ni o dá awọn eyi ti o wà nisisiyii? Ifihan 21:5 sọ fun wa pe, "Kiyesi i, mo sọ ohun gbogbo di ọtun". Eyi ni lati rú ifẹ

ọkàn olukuluku Onigbagbọ́ soke lati rin niwaju Oluwa ni iwa mimọ́ ati ni ododo ni ọjọ ayé rẹ̀ gbogbo, ki o si kun iṣẹ ki a le ri i ninu Rẹ̀ ni alaafia, lai labawọn ati ni ailabuku. Ki i ṣe pe ki oun ki o le ni ipa ninu Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun pẹlu Jesu nikan ṣugbọn ki oun ki o le ni anfaani lọpọlọpọ pẹlu lati wọ "Jerusalẹmu titun" ni opin ijọba Ẹgbẹrun ọdun, ki o si le rin ni ita wura gẹgẹ bi Johannu Apọsteli.

**A fi Idi Episteli Paulu Mulẹ**

Eredi ipamọra Oluwa ni fun igbala awọn wọnni ti a o ṣẹṣẹ gbà sinu Ijọ Ọlọrun. Sibẹ iye awọn eniyan ti o n wá sinu ayé pọ̀ lọpọlọpọ ju iye awọn ti o n wá sọdọ Kristi to bẹẹ ti o ba jẹ pe a mu akoko yá ju bi o ti yẹ lọ, pupọ ọkàn ni yoo sọnu ju iye ti yoo ri igbala lọ. Nitori naa, ẹ jẹ ki a ṣiṣẹ nitori dajudaju oru n bọ̀.

Nihin Peteru n fi idi ọrọ Apọsteli Paulu mulẹ pe o kún fun imisi ọgbọn Ọlọrun. O n sọ fun wa pe oun fara mọ ọrọ ti Paulu sọ ninu awọn Episteli rẹ̀ lori ipadabọ̀ Oluwa. Peteru wi pe awọn iwe Paulu ni awọn ohun ti o ṣoro lati yé ni. Awọn wolii ati awọn olukọ Iwe Mimọ́ n ri awọn iṣẹlẹ ni ọna jijin ju akoko tabi igba lọ, nigba miiran wọn a maa gboju fo awọn iṣẹlẹ miiran ti o wà laaarin awọn ohun ti wọn n sọrọ nipa rẹ. Eyi n fun wa ni ipilẹ itumọ awọn Ọrọ Iwe Mimọ́, ti n fi ẹsẹ ọrọ Iwe Mimọ́ kan tumọ ẹsẹ miiran; a si ni lati fi gbogbo ọrọ iṣipaya ifẹ ati ilana Ọlọrun pin Ọrọ Otitọ naa bi o ti yẹ. Peteru n sọ fun wa pe awọn ope tabi awọn afọju nipa ẹmi, ati awọn alaiduro nibi kan tabi alayidayida a maa lọ́ awọn Ọrọ Ọlọrun ti i ba fun wọn ni igbala bi o ba ṣe pe wọn tẹle e. Nipa lilọ́ awọn ọrọ wọnyii wọn n fa iparun wá sori ara wọn. Ikilọ ti o ga ni eyi. Nigba ti o n sọ nipa awọn Iwe Mimọ́ miiran ti wọn n lọ́, o sọ nipa awọn iwe Paulu gẹgẹ bi ọ̀kan ninu awọn iwe Majẹmu Titun ti a tẹwọgba ninu ijọ awọn Heberu.

**Didagba Ninu Oore-Ọfẹ**

Ni akotan ọrọ rẹ̀ nipa ewu aigba ipadabọ Kristi gbọ́, Peteru n gba awọn Onigbagbọ́ niyanju nipa imọ wọn ni ti ohun ti Ọlọrun pe ki wọn ṣọra ki a ma ba gbá wọn lọ nipa ọgbọ́n eniyan (ti o pe ni iṣina awọn eniyan buburu), ki wọn si ṣubu kuro ninu oore-ọfẹ. Eyi yoo jẹ́ ẹ̀ṣẹ si imọlẹ.

O si tun n gbà wọn niyanju lati maa dagba ninu oore-ọfẹ ati ninu imọ Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi. Eyi ni idakeji lilọ kuro ninu igbagbọ́. Imọ Ọlọrun ni idakeji aigbagbọ́. Ojiṣẹ Ọlọrun kan sọ bayii pe, nigba ogbó oore-ọfẹ a maa mu idagbasoke wá ki i ṣe ibajẹ; itẹsiwaju ki i ṣe ifasẹyin; aṣepe ki i ṣe ijafara. A n lọ lati ipá de ipá. Lai si oore-ọfẹ, ko le si imọ igbala. Eniyan a maa fẹ ṣogo ninu ọgbọ́n ayé ti ó ni, ṣugbọn Peteru n fi gbogbo ogo fun Kristi, nisisiyii ati titi lae.

**AWỌN IBEERE**

1. Akoko wo ni a n tọka si ninu ẹsẹ kẹta?
2. Ki ni awọn ẹlẹgan n fi ṣe ẹlẹya?
3. Otitọ wo ni ó dabi ẹni pe awọn ẹlegan ṣe alaimọ̀?
4. Ki ni ṣe ti a ṣe fa bibọ Oluwa sẹyin?
5. Darukọ diẹ ninu awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ nigba Ọjọ Oluwa.
6. Pẹlu gbogbo imọ nipa Ọjọ Oluwa irú eniyan wo ni awọn Onigbagbọ́ yẹ ki o jẹ́?
7. Ireti wo ni a gbé ka iwaju awọn Onigbagbọ́?
8. Ki ni ikilọ ati ọrọ iyanju ti Peteru fi pari Episteli yii?